

# Iwe Iroyin HapMap

Iwe yi jade ni orukọ ilé isẹ iwadi Coriell fun iwadi imọ ijinlẹ ninu aisan ti o n se iwadi imọ ijinlẹ lori aisan, Apa keji, Ọdun 2005

*Lati ọdun kẹta sẹyin ti a ti bẹrẹ isẹ àgbàse HapMap, a ti ri wipe isẹ naa ni iwulo pàtàkì fun awọn awadi ninu imọ ijinlẹ aisan. Awọn ogbontarigi ninu ọmọwé ni orilẹ èdè àgbáyé ni igbagbọ wipe elo pàtàkì yi, yi o ran wọn lọwọ lati fi le mọ bi awọn Jiini se ni ọwọ si awọn arun ara ati aisan bi akàn, aisan ọkàn, itọ suga ati aisan ibanujẹ ọkàn. Yi o tun ran wọn lọwọ lati fi le mọ awọn Jiini ti o ni ọwọ si bi oògùn se nse ise ni ara eniyan.*

## Ilosiwaju kini ti a ti se pẹlu HapMap

Pẹlu ajẹyẹ àti ìpàdé nla ni osù kẹwa ọdun 2005 ti a wa yi ni ìlu Salt Lake City, Utah ni orilẹ ede Amẹrika, awọn ti o jẹ asiwaju HapMap ti a pe ni International HapMap Consortium ti wipe awọn ti pari kókó isẹ HapMap yi. Isẹ pàtàkì yi o ni iroyin lọpọ lọpọ. O si tun fi awọn iyatọ han ti o wa ninu Jinni ẹjẹ ayẹwo lati ọdọ adọrinlelọgọrunmeji eniyan. Awọn ẹjẹ ayẹwo ti a lo fun isẹ yi wa lati ọdọ:

- Awọn ọmọ Yoruba ni ilu Ibadan ni orilẹ ede Naijiria
- Awọn araa Jepaanu ni ilu Tokio ni orilẹ ede Jepaanu
- Awọn Han Shainisi ni ilu in Beijingi, ni orilẹ ede Shaina
- CEPH (ni ilu Utah, agbègbè awọn ọmọ Amerika ti o ni irandiran si ila orun ati guusu Yuroopu).

*Ẹ ma reti apa keji eto yi*



*"Awọn eniyan pupọ kaakiri àgbàyé ni wọn ti kopa ninu isẹ àgbàse HapMap yi, sugbọn a dupẹ lọpọ lọpọ fun awọn eniyan ti wọn fi ẹjẹ sílẹ. Ti ko ba kin se iranlọwọ wọn, awa ko ni le se isẹ àgbàse yi rara rara."*

- Ọrọ yi wa lati ẹnu Dokita Yusuke Nakamura, olórí awọn ẹgbẹ awadi HapMap ni RIIKEN ati Tokio Yunifasiti ni ilu Tokio ni orilẹ ede Jepaanu

## Nipa ile iwadi Coriell

Ilé iwadi Coriell fun iwadi imọ ijinlẹ ninu aisan ni ilu Camden, ni ilẹ Niu Jẹsi (New Jersey), o jẹ ile isẹ iwadi agbateru ti a ko da silẹ fun owo ti won si tu ni orukọ pàtàkì ni gbogbo orilẹ èdè àgbáyé ni isẹ ti wọn ti se nipa iwadi Jiini ati itọju awọn sẹẹli. Ilé itọju sẹẹli wọn ti wọn nlo fun iwadi ni o jẹ eyi ti o tobi ju ni gbogbo orilẹ èdè àgbáyé. O si tun jẹ koko ati eyi ti ko se rọpo fun awọn asepapọ awọn ogbontarigi ọmowé ni gbogbo àgbáyé.





## Bi ẹ se le kan si wa

A ran agbègbè yin lọwọ kan ke si wa pelu ifọwọsowọpo awọn ẹgbẹ amòye ni agbègbè yin eyi ti a pe ni Community Advisory Goup, ki a ba le mọ orisirisi iroyin ti o wun yin lati gbọ. Dokita Jeanne Beck ni o jẹ asiwaju isẹ iwadi HapMap ni ilé iwadi Coriell. Ohun ni o tun jẹ alakoso fun awọn iwadi ati awọn agbègbè ti wọn ba wa sowọpọ. Ẹ le kan si ni adresi ti a ko sihin:


Dr. Jeanne Beck
Director Coriell Cell Repositories
Coriell Institute for Medical Research
403 Haddon Avenue
Camden, New Jersey 08103, USA

Ago rẹ:
800-752-3805 ti ẹ ba pe ni orilẹ ede Amerika
856-757-4822 ti ẹ ba pe lati ilu miran

Faksi:
856-757-9737

Emaili:
jbeck@coriell.org

Adresi rẹ ni intaneti:
http://www.coriell.org



# Ati ri Jiini aisan akọkọ pẹlu HapMap

Ki a to pari apa kinni isẹ àgbàse HapMap ni a ti lo HapMap yi lati fi se iwadi awọn Jiini ti o lọwọ si awọn aisan ti o ma nse awọn eniyan. Isẹ aseyege akọkọ ninu riri awọn Jiini kankan ti o lọwọ si aisan ojú ti o wa pẹlu ọjọ ori.

Aisan yi o kan awọn marunlelogun si ọgbon egberunlegeberun eniyan. O si tun jẹ ikan ninu awọn koko ohun ti o nfa afọju kaakiri àgbáyé.

Daju daju, awọn Jiini ti a ri yi ko ran aisan oju yi ni kia kia. Sugbọn o jẹ ìgbésẹ pataki akọkọ. Pẹlu imọ tuntun yi, o se se ki o jẹ wipe awọn awadi yi o se ọna lati ri awọn eniyan ti o ni ẹya Jiini yi, eyi ti oyinbo pe ni (the “variant”) ti o nfaa ki awọn eniyan ni aisan yi. Ti a ba se idanwo, ti a ba si ri awọn eniyan ti o ni ẹya Jiini yi, awọn dokita wọn yi o fun wọn ni ilana nipa ohun ti wọn ni lati se ki wọn ma baa fọju – awọn ohun bi ki á má mu sìgá, ki a ma duro sinu oorun pupọ ju, ki a maa jẹ ẹfọ pupọ ati ki a maa lo ri dokita le sẹsẹ fun ayẹwo oju. Mimo nipa awọn Jiini ti o ni ọwo si aisan oju yi ma ran awọn dokita lọwọ lati tete ri aisan yi lara awọn eniyan ti o ti nii. O si tun le ran wọn lọwọ lati le ran aisan naa dara dara.

A si tun maa ri awọn ohun miran lọpọ lọpọ ni ọjọ iwaju nitoriwipe awọn awadi ti nlo HapMap lati fi mọ awọn Jiini ti o lọwọ si awọn arun bi itọ suga, arun kidirin, ati isẹ ti oogun nse ni ara awọn eniyan. Ni inu iwe iroyin HapMap ni ọjọ iwaju, awa yi o sọrọ nipa awọn ohun tuntun ti a ri ninu iwadi yi ati awọn ise iwadi omiran.



*o bẹrẹ lati ewe kini*

“Awọn eniyan pupọ kaakiri àgbáyé ni wọn ti kopa ninu isẹ àgbàse HapMap yi, sugbọn a dupẹ lọpọ lọpọ ni ọwọ awọn eniyan ti o fi ẹjẹ silẹ. Ti ko ba si ti iranlọwọ wọn, awa ko ni le se isẹ àgbàse yi rara rara.” Eyi jade lati enu Dokita Yusuke Nakamura, olórí awọn ẹgbẹ awadi HapMap ni RIIKEN Yunifasiti ni ilu Tokio ni orilẹ ede Jepaanu.

Ilọsiwaju yi jẹ igbesẹ kini lati se isẹ ti yi o wulo lọpọ lọpọ ni ọjọ iwaju. Laipẹ yi, awọn awadi o bẹrẹ igbesẹ tuntun ninu isẹ àgbàse yi. Wọn yi o se igbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo lati awọn ẹgbẹ meje si. Eyi jẹ:

- Awọn Luya lati Webuye, ni orilẹ ede Kenya
- Awọn Maasai ni Simba, ni orilẹ ede Kenya
- Awọn eniyan ti irandiran wọn wa lati ilu Afrika ni awọn ilu ti nbẹ ni isalẹ-osi orilẹ ede Amerika
- Awon eniyan ti o wa lati agbegbe Han Shainisi ni Denver, Colorado ni orile ede Amerika
- Awọn Toskani ni Toskani, ni orilẹ ede Itali.
- Awọn ti wọn wa lati ilu Mesiko, ti wọn si ngbe ni ilu Los Anjẹlis, Kalifonia ni orilẹ ede Amerika
- Awọn Gujarati lati orilẹ ede India ti wọn ngbe ni ilu Houston, Texas ni orilẹ ede Amerika

Wiwo awọn iyato ti o wa ni ẹya Jinni awọn eniyan wọn yi, yi o ran awọn awadi HapMap yi lọwọ lati mọ bi awọn orisun iwọn Jiini lati ẹjẹ ayẹwo awọn ẹgbẹ mẹrin akọkọ se le jẹ iranlọwọ lati ri awọn Jiini ti o nfa aisan ni ara awọn eniyan ti o ngbe ni awọn ilu omiran kaakiri àgbáyé tabi ti wọn ni irandiran sibẹ.

“Bi a se nse igbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo lati ẹgbẹ omiran ni isẹ HapMap yi o wulo si lọpọlọpọ ni ọna orisirisi.” Eyi wa lati ẹnu Dokita David Altshuler, olórí awọn ẹgbẹ HapMap ni ile ise iwadi ti wọn pe ni, The Broad Institute ati ile iwosan nla, Massachusetts General Hospital ni ilu Boston, Massachusetts ni orilẹ ede Amerika. Gbogbo agbègbè ti o fi ẹjẹ ayẹwo silẹ fun ise àgbàse yi ni o da yatọ, sugbọn gbogbo awọn agbègbè tí wọn kopa ninu ise yi ni wọn ni ohun kan ti o pa wọn pọ: Ohun ni wipe wọn se igbesẹ ati iranlọwọ pataki ti yi o wulo pupọ ni ọjọ iwaju fun ilọsiwaju alafia awọn eniyan ni gbogbo àgbáyé.



> *“Bi a se nse se igbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo lati ẹgbẹ omiran, ni isẹ HapMap yi o wulo si lọpọlọpọ ni ọna orisiris.”*
>
> - Eyi wa lati ẹnu Dokita David Altshuler, olórí awọn ẹgbẹ awadi HapMap ni ile isẹ iwadi The Broad Institute ati ile iwosan nla Massachusetts General Hospital ni ilu Boston, Massachusetts ni orilẹ ede Amerika

# Awọn iroyin pataki

## Iwe iroyin yi sọrọ nipa awọn agbègbè mẹta ti o kopa ninu isẹ yi

### Awọn ara Han Shanisi ni orilẹ ede Beijingi ni ilu Shaina.

Awọn agbègbè Han Shainisi ni o tobi ju lọ ninu awọn ẹgbẹ mẹrindinlọgọta ni orilẹ ede Shaina. Ẹgbẹ wọn nikan ni o si tun pọju lọ ni orilẹ ede àgbáyé. Adorun ninu ogorun wọn ati ju be lọ ni o je Shainisi ati wipe mokandinlogun ninu ogorun gbogbo ọmọ ẹgbẹ àgbáyé ni o jẹ ọmọ ẹgbẹ Han. Orukọ ti a pe ni "Han" wa lati ẹgbẹ idile ọba Han ti o jọba lori awọn ilẹ ti o se koko ni ilu Shaina lati ọdun kejilelugba ki a to bi Jesu si ọdun ogunlelugba lẹhin iku Jesu.

A se igbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo ti a gba lati ọdọ awọn Han Shanisi ni ilu Beijing, ni apá kini ati apá keji ise àgbàse HapMap yi. Awọn ẹjẹ ayẹwo yi wa lati ọdọ awọn eniyan ti o ngbe ni ilẹ Yunifasiti Beijing Normal University (BNU), ti o jẹ ile iwe unifaisiti nla ti o ni orukọ pàtàkì, ti o si tun ni ile akẹkọ marunlelogun ati awọn ile isẹ orisirisi, awọn ile isẹ iwadi mokanla, ile akẹkọ alẹ ati awọn orisirisi ẹkọ idagbasoke. Awọn eniyan ẹgbẹrunmarundinlogoji ni wọn ngbe ni agbègbè BNU yi. Ninu wọn lati ka awọn akẹkọ, awọn ọmọ ile iwe unifasiti, awọn ara ile wọn, awọn osisẹ unifasiti ati ọpọlọpọ awọn ọmọwe ati awọn onisẹ ọwọ. Awọn eniyan lati orisirisi ile ni wọn kopa ninu isẹ igbeyẹwo HapMap yi. Pẹlu awọn eniyan lati ilu mejilelogun ninu mọkanlelọgbọn ilu nlanla ti o wa ni ilu Shaina, awọn ilu ti o da duro ati awọn ilu kékèèké.

Awọn ti o kopa ninu isẹ yi mọ fun ara wọn wipe isẹ àgbàse HapMap yi o wulo fun ilọsiwaju alafia ọmọ eniyan ati fun iwadi ninu ijinle aisan lorisirisi. Inu wọn si dun lọpọlọpọ lati le ko pa ninu isẹ yi fun ilu Shaina. Ni ibẹrẹ awọn ibeere kankan wá lati ọdọ awọn eniyan nipa bi a o ti se maa lo awọn ẹjẹ ayẹwo wọn yi ni ọjọ iwaju ati nipa ibi ti a o tọju awọn ẹjẹ ayẹwo naa si ati bi awọn ọmọwe ti se maa ri lo. Bẹẹ naa, inu ẹgbẹ amòye ti a pe ni CAG dun pupọ lati maa gba iroyin nipa ilosiwaju isẹ àgbàse yi ati bi awọn ẹgbẹ ọmọwe ni awọn ilu orisirisi omiran ti se nlo awọn ẹjẹ ayẹwo wọn yi.



*Gẹgẹ bi awọn ẹgbẹ amòye agbègbè Community Advisory Group ti Unifasiti Beijing Normal University ti wi (ẹ wo aworan ti o wa loke), inu awọn eniyan ti nwọn ngbe ni ile Unifasiti yi dun pupọ lati fi ẹjẹ ayẹwo silẹ.*

### Awọn Shainisi ti o ngbe ni aarin ilu Denver, Colorado ni ori lẹ ede Amerika

Ilu Denver, Colorado ti o ni awọn eniyan ti o to ọgọrunmarun egeberun eniyan ati ju bẹẹ lo, o jẹ ilu fun ọgọrun ẹgberun awọn ọmọ Asia. Awọn marundinlogun ẹgbẹrun, tabi paapaa awọn mẹfa ati abọ ninu wọn ni o jẹ Shainisi. Awọn ọmọ Shaina ti o ngbe ni aarin ilu Denver, Colorado jẹ ẹgbẹ ti o yatọ lorisirisi. Ọpọlọpọ ninu wọn wa si ilu Amerika lati orisirisi ilu, wọn si tun ni orisirisi asa ibilẹ. Ninu wọn ni a ti ka awọn ti o wa si agbègbè yi ni ọdun 1800, awọn akẹkọ ti o nlọ si ile iwe ni Denver ni igbẹyin ọdun 1940, awọn eniyan ti o wa lati ori lẹ ede Taiwan ati HongKong, nigba ti wọn si ọna fun igbelu ni ilẹ Amerika ni 1965 fun gbogbo ilu omiran, ati awọn eniyan lati ori lẹ ede Vietnam ati Shaina ti o wa si ilu Amerika ni arin ati igbẹyin ọdun 1970.

Awa yi o se agbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo ti a gba ni ọwọ awọn Shainisi ni ilu Denver, Colorado ni apá kẹta isẹ àgbàse HapMap yi. Ni pato, inu awọn ẹgbẹ yi ati awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG dun lọpọlọpọ lati ko pa ninu isẹ yin fun agbègbè wọn ati lati fi ẹjẹ silẹ. Pupọ ninu wọn ni o lero wipe ise iwadi Jiini yi, yi o wulo fun ilọsiwaju alafia ọmọ eniyan ati fun ki a ma baa ni aarun.

Awọn eniyan yi tun sọ wipe awọn ni ifunra si isẹ yi, nitori naa, wọn fẹ ki awọn awadi orisun iwọn Jiini yi ki wọn se isẹ iwadi wọn ni ọna ti o tọ ati ọna ti o yẹ, ati ni ọna otitọ. Wọn si fẹ ki wọn mọ nipa oririsi awọn eniyan Shainisi ati orisirisi asa ibilẹ wọn, ati ki wọn ma ya awọn ọmọ Shainisi agbègbè wọn si ọtọ. Awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG yi nreti pẹlu idunnu lati ri bi a se maa lo awọn ẹjẹ ayẹwo ti a gba ni agbègbè wọn fun isẹ iwadi orison iwọn Jiini ati ifọwọsowọpọ wọn pẹlu ile ise iwadi Coriell.



*Ere ajọyọ ti a pe ni Dragon Boat Festival jẹ sise pataki lọdọọdun fun awọn ẹgbẹ ọmọ Shainisi ti o wa ni ilu Denver ni Colorado.*

## CEPH (Awọn ọmọ Amerika ti wọn ni irandiran ni ila orun ati guusu ni ori lẹ ede Yuroopu)

Awọn ẹjẹ ayẹwo ti a se igbeyẹwo rẹ fun apá kini ati apá keji isẹ àgbàse HapMap ni eyi ti a gba ni ọdun 1980 ni ọwọ awọn eniyan ni Utah ni ori lẹ ede Amerika, awọn eyi ti ọpọlọpọ ninu irandiran wọn wa lati ila orun ati guusu ni ori lẹ ede Europe. Orukọ ti a pe ni "CEPH" ni o nje Centre d'Etude Polymorphisme Humain. Eyi ni alagbase ti o kọkọ gba awọn ẹjẹ ayẹwo wọn yi. Awọn ẹjẹ ayẹwo alagbase CEPH wa lati ọdọ idile ti o ni agbagba ati awọn ọmọde. Wọn dẹ si ti tun lo awọn ẹjẹ ayẹwo wọn fun iwadi orisun iwọ Jiini pataki omiran Igbeyẹwo awọn ẹjẹ ayẹwo yi fun HapMap yi o jẹ ki awọn awadi yi le sisẹ si le awọn ohun ti o ti wa nilẹ nipa awọn eniyan yi.

Lara awọn eniyan ti o fi ẹjẹ ayẹwo silẹ fun alagabse CEPH ti kú ni aarin ọdun marundinlọgbọn ti wọn ti gba awọn ẹjẹ ayẹwo yi. Awọn omiran si ti lọ si ilu miran, sugbọn ọpọlọpọ ninu awọn ti o fi ẹjẹ ayẹwo silẹ ni o gbé ni awọn ilẹ ti o sun mọ ilu Salt Lake City ni Utah (ilu ti o ni igba ẹgbẹrun eniyan ati ju bẹẹ lọ). Ilu Salt Lake City jẹ ilu ti o wa ni isalẹ oke ti awọn eniyan si mọ fun ọsà nla ti a pe ni Great Salt Lake. Eyi jẹ ọsà ti o tobi ju lọ ni ila orun apa osi ori lẹ ede àgbáyé. Ilu Salt Lake City ni o tun jẹ olu ile isẹ awọn onigbagbo Church of the Latter Day Saints (ti a tun pe ni Mormon Church).

Wọn ko da ẹgbẹ amòye agbègbè CAG kan kan pato fun awọn ti o fi ẹjẹ ayẹwo silẹ fun alagbase CEPH, sugbọn pupọ ninu awọn ti o fi ẹjẹ ayẹwo silẹ ni wọn si nran awọn awadi lọwọ ti o gba awọn ẹjẹ ayẹwo lọwọ wọn pẹlu isẹ wọn titi di ọjọ oni Aseyọri awọn ifọwọsowọpọ ọjọtipẹ wọn yi ati iwulo awọn ẹjẹ ayẹwo CEPH fun isẹ iwadi ati fun ilo titi di ọjọ oni o jẹ gẹgẹ bi ohun ti a lero lati se pẹlu isẹ àgbàse HapMap bi a ba ti ngba awọn ẹjẹ ayẹwo lati awọn agbègbè omiran.



*Awọn ẹjẹ ayẹwo alagbase CEPH wa lati ọdọ awọn idile ti o ni awọn agbagba ati ọmọde ni ilu Utah ni ori lẹ ede Amerika, ati ti ọpọlọpọ ninu irandiran wọn wa lati ila orun ati guusu ni ori lẹ ede Yuroopu.*

Awa yi o sọrọ nipa awọn agbègbè to ku ti wọn ko pa ninu isẹ yi ninu awọn iwe iroyin meji ti o tẹle eleyi. Awa yi o si tun maa to yin leti leseẹsẹ nipa isẹ àgbàse Hap Map yi ati awọn iwadi pataki.

Ẹ o ri itẹjade iwe iroyin HapMap yi ni ibudo ori itakun àgbáyé ni adresi ti a kọ sihin. Eyi jẹ: http://www.coriell.org/ccr/hapmap.html. Ẹ tun le ri awọn iroyin pataki ni adresi àgbàse gbogbo ori lẹ ede àgbáyé ni orukọ HapMap ti a pe ni International HapMap Project. Eyi jẹ, http://www.hapmap.org.

# Ifọwọsowọpọ pẹlu awọ àgbègbè

Lati le ran isẹ awọn agbègbè lọwọ ti wọn fi ẹjẹ ayẹwo silẹ fun HapMap ni a se da ẹgbẹ amòye agbègbè, eyi ti a pe ni Community Advisory Group (CAG) silẹ ni gbogbo ibi ti a ti gba ẹjẹ fun àgbàse yi. Ile isẹ iwadi Coriell ti o jẹ alamojuto awọn ẹjẹ ayẹwo ti a tọju, ti se tan lati feti silẹ si awọn ọrọ ti awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG ni lati sọ si bi a se le fi iroyin nipa isẹ wa ati awọn ẹjẹ ayẹwo wọn yi to awọn eniyan leti ni ọna ti o dara ju eyi ti a nlo nisisiyi lọ.

Awọn ọrọ naa yi o wulo paapaa lẹhin igba ti a ba pari isẹ àgbàse HapMap yi, nitori wipe a yi o lo awọn ẹjẹ ayẹwo fun HapMap ati fun awọn isẹ iwadi Jiini ni ọjọ iwaju. "O see se ki o jẹ wipe a ko ni ri awọn ohun buburu tun-tun ti o yatọ si eyi ti a ti ri ni isẹ àgbàse HapMap. Sugbọn ile isẹ iwadi Coriell ti se tan lati maa fi iroyin to awọn agbègbè leti ni igba gbogbo nipa gbogbo awọn isẹ iwadi naa." Eyi jẹ gẹgẹ bi ọrọ ti o wa lati ẹnu Dokita Jeanne Beck, ti o jẹ asiwaju ile itọju awọn ẹjẹ ayẹwo ti a pe ni Coriell Cell Repositories. Lati le fun awọn eniyan ni iroyin naa, ile isẹ iwadi Coriell ma npin awọn iwe ètò nipa isẹ rẹ ni osun mẹta mẹta fun awọn amòye agbègbè CAG kan kan. Ninu rẹ, a tun kọ gbogbo awọn isẹ iwadi ti a se lori gbogbo awọn ẹjẹ ayẹwo ti a gba ni ọwọ awọn eniyan ni awọn.



Awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG tun wulo pataki lati fi iroyin to gbogbo awọn agbègbè wọn leti. Awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG kan kan nlo awọn asa ibilẹ lati fi iroyin to awọn eniyan leti. Lara rẹ ni wipe wọn njoko sọ ọrọ nipa isẹ àgbàse yi pẹlu awọn eniyan miran ni agbègbè wọn ati wipe wọn si tun npin awọn iwe iroyin HapMap yi kaakiri.

Awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG kan kan ni awọn ibi ti o see se, lero lati da ile isẹ intanẹti silẹ lati fi gbe awọn iroyin pataki jade, bi orukọ gbogbo awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG ati iroyin nipa ohun ti o sẹlẹ ni awọn ipade wọn. Wọn si tun le gbe awọn akosilẹ nipa HapMap ati awọn ise iwadi rẹ jade, awọn akọsilẹ nipa boya isẹ iwadi orisun iwọn Jiini jẹ ohun ti o tọ tabi boya o jẹ ohun ti o yẹ tabi o jẹ ohun ti ko ru ofin. Wọn si tun le gbe iroyin HapMap jade lori ibudo ori itakun àgbáyé.

Ile isẹ iwadi Coriell yi o ran awọn ẹgbẹ amòye agbègbè CAG lọwọ pẹlu owo ti wọn ba fẹ ma gbe iroyin jade lori intaneti sugbọn ti wọn ko ni owó lati se. Titi di ọjọ oni, a ti ri awọn ti o ti da adresi intaneti kan silẹ, ti o njẹ (http://snp.ims.u-tokyo.ac.jp/CAG/JCAG/JCAG.html.ja). Awa yi o si tẹ awọn adresi intaneti omiran bi wọn ba se njade si inu awọn iwe iroyin ni ọjọ iwaju. E si le ri wọn ka ni adresi intaneti ile isẹ iwadi Coriell ti nje (http://www.coriell.org) ati adresi intaneti àgbàse ori lẹ ede àgbáyé ni orukọ HapMap ti a pe ni International HapMap Project. Eyi si ni (http://www.hapmap.org). A lero wipe iranlọwọ yi yí ó jẹ ki awọn eniyan ti o jẹ wipe wọn ko le lo intaneti le ko pa si ninu isẹ iwadi yi ati ki wọn ba le mọ si nipa awọn agbègbè omiran ti awọn eniyan ti fi ẹjẹ ayẹwo silẹ ni ilu omiran ni ori lẹ ede àgbáyé. O tun le see se ki o jẹ wipe wọn maa le kọwe si awọn eniyan ni awọn agbègbè omiran ti awọn eniyan ti fi ẹjẹ ayẹwo sile. Gẹgẹ bi ọrọ lati ẹnu Dokita Charles Rotimi, asiwaju awọn ẹgbẹ ni Howard Unifasiti ni ilu Washington DC (ni ori lẹ ede Amerika), ti o gba awọn ẹjẹ ayẹwo lati ori lẹ ede Naijiria ati Kenya pẹlu ifọwọsowọpọ awọn ọmọ onilu, "A lero wipe laipẹ awa yi o le jẹ ki awọn eniyan ri isẹ àgbàse HapMap yi gẹgẹ bi isẹ fun ori lẹ ede àgbáye larin awọn agbègbè ti wọn ko pa ninu isẹ yi."

*""Alero wipe laipẹ awa yi o le jẹ ki awọn eniyan le ri ise àgbàse HapMap yi gẹgẹ bi isẹ fun ori lẹ ede àgbáye larin awọn agbègbè ti wọn ko pa ninu isẹ yi."*

- Eyi jẹ gẹgẹ bi ọrọ lati ẹnu Dokita Charles Rotimi, asiwaju awọn ẹgbẹ awadi HapMap ni Howard Yunifasiti ni ilu Washington, DC ni ori lẹ ede Amerika

Coriell Institute for Medical Research
403 Haddon Avenue
Camden, New Jersey 08103 USA
E si le pe ago wa,
tel: 800–752-3805 ti ẹ ba pe ni ori lẹ ede Amerika • 856–757-4822 ti ẹ ba pe lati ilu omiran
Faksi: 856-757-9737
Linki wa ni lori intaneti ni
http://www.coriell.org